Ọlọ́run Ni Olùtúmọ̀ Ara Rè



Baba wa Ọrun, Ọrọ kan lati ọdọ Rẹ yoo ni itumọ ju eyi ti gbogbo eniyan nigbakuugba lee ṣe tabi sọ, nitoriti awọn eniyan n duro lati ri Ọ. A dupẹ lọwọ Rẹ nitoripe awọn kan wa ti wọn n reti, wọn n foju sọna wipe ki nkankan ṣẹlẹ. Nigbati awọn eniyan ba si n pongbẹ fun nkankan, ibu n pe Ibu, Ibu kan nilati wà lati dahun ipe yẹn. Idi ti a fi wa nibi ni aṣalẹ yii niyẹn, nitoripe o wa lọkan awọn oniwaasu wọnyi, ati awọn eniyan, lati pe wa papọ wipe ki a beere fun ojurere ati ibukun Rẹ, pelu igbagbọ wipe Iwọ yoo mu awọn alaisan lara da, Iwọ yoo si gba awọn ẹlẹṣẹ là, Iwọ yoo si fi Ọrọ Rẹ han.

2 A gbadura, Baba wa Ọrun, wipe ki o ṣe nkan yii fun wa bi a ṣe n fi irẹlẹ duro de Ọ, ni alaalẹ. Jẹ ki o wá—ani itujade Ẹmi Mimọ, jẹ ki olukuluku fọju si ohun ti o wà ni ayika wọn ayafi Ọlọrun. Jẹ ki igbe nla kan jade lọ lati ọ̀dọ̀ awọn eniyan, ki wọn maa pongbẹ fun Ọlọrun, titi ti isọji nla yoo fi bẹ silẹ ni gbogbo agbegbe yii, ki gbogbo ijọ si kun fun awọn eniyan, ki awọn ẹlẹṣẹ maa kigbe wipe ki Ọlọrun ṣaanu, ati pe—ati pe ki Ẹmi Mimọ mu awọn alaisan lara da, ki awọn arọ maa rin, ki awọn oku maa ji dide, ki O si fun wa ni awọn nkan wọnyi ti a ti ṣeleri ninu Ọrọ Rẹ.

3 Wá, Jesu Oluwa, mu ileri Rẹ ṣẹ. Wá si aarin wa ni aṣalẹ yii. A gbagbọ wipe ọkannaa ni Ọ lana, loni, ati titi lae, wipe awọn ileri Rẹ kò lee kuna. Ọrun oun aye yoo kuna, ṣugbọn Ọrọ Rẹ ki yoo kuna. Ṣí wa ni iyè. Jẹ ki Ẹmi Mimọ wa ro oko mọ́ ọkan wa. Jẹ ki a ṣí iyè wa si Ẹmi ati agbara Ọlọrun ni aṣalẹ yii, ki Ó lee fi awọn Ọrọ Ileri Rẹ han nipasẹ wa. Nitoriti a beere rè ni Orukọ Jesu. Amin.

4 Njẹ ni aṣalẹ yii, ẹyin ti ẹ maa n kiyesi iwe kika, ẹ jẹ ki a ṣí Bibeli wa si Iwe Peteru Keji, ki a bẹrẹ pẹlu ẹsẹ kẹẹdogun, ki a lee sọrọ lori Iwe Mimọ fun iṣẹju diẹ.

> *Emi yoo si maa ṣaápọn pẹlu, ki ẹyin ki o lee maa ranti nkan wọnyi nigbagbogbo lẹyin iku mi.*
>
> *Nitori ki i ṣe bi ẹniti n tọ ìtàn asán lẹyin, ti a fi ọgbọn-kọgbọn là silẹ, ni awa fi agbara ati wíwá Jesu Kristi Oluwa wa han yin, ṣugbọn ẹlẹri ọla nla rẹ̀ ni awa n ṣe.*

5 Mo fẹran iyẹn, “ẹlẹri.” Ki i ṣe ìtàn asán kan. Awa jẹ ẹlẹri ohun ti a n sọrọ nipa rẹ.

Nitoriti o gba ọla oun ògo lati ọdọ Ọlọrun Baba, nigbati iru ohùn nnì fọ̀ si i lati inu ogo nla naa wa pe, Eyi ni ayanfẹ ọmọ mi, ẹniti inu mi dun si jọjọ.

Ohùn yii ti ó ti Ọrun wá ni awa si gbọ́, nigbati awa n bẹ pẹlu rẹ̀ lori oke mimọ naa.

Awa sì ní ọrọ asọtẹlẹ ti ó fẹsẹ mulẹ ju bẹẹ lọ; eyiti o yẹ ki ẹyin *ki* o *kiyesi bii fitila ti n tàn nibi…okunkun, titi ilẹ yoo fi mọ́, ti irawọ owurọ yoo si yọ ni ọkan yin.*

Ki ẹ kọ́ mọ eyi, pe ko si ọkan ninu asọtẹlẹ inu Iwe-Mimọ ti o ni itumọ ìkọ̀kọ̀.

Nitori asọtẹlẹ kan ko ti ipa ìfẹ́ eniyan wá rí: ṣugbọn awọn eniyan n sọrọ lati ọdọ Ọlọrun bi a ti n dari wọn lati ọwọ Ẹmi Mimọ wa.

6 Ki Ọlọrun fi ibukun Rẹ si kíkà Ọrọ Rẹ. Ni bayi, emi yoo fi eyi ṣe akori ọrọ: *Ọlọrun Ni Olutumọ Ara Rẹ̀.*

7 A n gbe ni ọjọ idaru-dapọ. A n gbe ni ọjọ ti awọn ọkunrin ati obinrin kò tilẹ mọ ohun ti o yẹ ki wọn ṣe. O dabi ẹni wipe ohun gbogbo ti daru. Ninu ohun gbogbo, o dabi ẹni wipe ọpọlọpọ oniruuru ọna ni o wà lati wò. Satani ni o n ṣe iyẹn.

8 Bayi, Ọlọrun kò lee dá awọn eniyan kan lẹjọ ni ododo, tabi ni ọna èṭọ́, bikoṣepe òṣùwọ̀n kan wà ti Oun yoo fi da wọn lẹjọ. Bibeli si wipe Oun yoo ṣe idajọ gbogbo eniyan nipasẹ Jesu Kristi, Jesu Kristi si ni Ọrọ naa. Ninu iwe Johanu Mimọ, ori kinni, o sọ pe:

Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa.

Ọrọ naa si di ara, o si n ba wa gbe,…

9 Ohun gbogbo ti a jẹ́ loni ni ifihan awọn ero inu Rẹ. Ninu Ọlọrun… Lakọkọ na, Oun ki i tilẹ iṣe Ọlọrun, Ọlọrun, a o kan pe E ni “Ẹni Ainipẹkun.” Oun ki i ṣe Ọlọrun, nitori Ọrọ naa (Ọrọ Gẹẹsi) ti a n pe ni *Ọlọrun* tumọ si “ohun ti a n sìn” ko si si ohunkohun lati sin Oun. Nitorinaa, Oun ni Ẹni Ainipẹkun, Oun—ni koko Orisun ọgbọ́n. Ninu Orisun gbogbo ọgbọn yii, ko si ohun ti o kere, ti o kere julọ, tabi ohunkohun, ko si imọlẹ nibikibi, irawọ, oṣupa, ko si ohunkohun miiran. Ọlọrun, ohun ti a mọ gẹgẹbi Ọlọrun, Ẹmi nla naa ti o jẹ Ainipẹkun (kò ni ibẹrẹ, kò ni opin), O wà nibẹ. Awọn èrò kan wà ninu Rẹ: ero lati jẹ Ọlọrun, lẹyinnaa ero Rẹ lati jẹ Baba, ero lati jẹ Ọmọ, ero lati jẹ Olugbala, ero lati jẹ Oluwosan. Gbogbo awọn ero wọnyi wa ninu Rẹ. Ni bayi, O…Awọn nkan wọnyi ti o ti farahan lati igba naa jẹ awọn ero Rẹ ti a n fihan.

10 Ohun ti mo ni lọkan nipa *ero*, ni awọn “ero inu” Rẹ. Pẹlupẹlu—*Ọrọ* jẹ “ero ti a fihan.” Iyẹn wa ninu ero Rẹ. Nigbati O sọ pe, “Jẹ ki o wà,” ó sì wà. “Jẹ ki o wà,” o si wà.

11 Ni bayi, ẹ ranti, ẹyin Kristẹni jẹ ero Rẹ ki aye to wà. Ẹyin si ni ifarahan ero Rẹ. Ki aye to wà, ẹ ti wa ninu Kristi, (amin) ninu Ọlọrun ni atetekọṣe. Ṣe ẹ mọ, iyẹn ni o sọ yin di eniyan Tirẹ. Gbogbo rẹ si jẹ Ọlọrun, funra Rẹ, ti O n fi ara Rẹ han ni gbangba, ki a lee fi ọwọ kan-An, ki a lee ri I, ati—ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ohun ti Ọlọrun jẹ niyẹn, ani gbogbo rẹ.

12 Awọn eniyan maa n sọ pe, “Itumọ…” Mo n sọrọ laipẹ yii nibi ipade kan, ọkunrin kan sọ fun mi, o ni, “Arakunrin Branham, o ní itumọ òdì. O kò tumọ Iyẹn daradara.”

13 A maa n gbọ…Wọn yoo lọ sinu Ijọ Eleto, wọn yoo si sọ pe “awọn Ijọ Onitẹbọmi ko tumọ Rẹ daradara.” Ijọ Onitẹbọmi yoo sọ pe, “Awọn Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ko tumọ Rẹ daradara.” Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ yoo sọ pe “Ijọ—ijọ Ọlọrun Kanṣoṣo ko tumọ Rẹ daradara.” Awọn Ijọ Ọlọrun Kanṣoṣo yoo sọ pe, “awọn Ijọ Ìpéjọpọ̀ ko tumọ Rẹ daradara.” Olukuluku ni o n sọ pe ẹnikeji ko tumọ Rẹ daradara.

14 Ọlọrun ni Olutumọ Ara Rẹ! Oun kò nilo ẹnikẹni lati ṣe itumọ fun-Un. Oun ni o n ṣe itumọ fun Ara Rẹ. Eniyan wo ni o lee tumọ Ọlọrun? Ọlọrun ni Olutumọ Ara Rẹ.

15 Peteru n sọrọ nibi yii, a ri i wipe ni atetekọṣe, nigbati Ọlọrun sọ pe, “Jẹ ki imọlẹ ki ó wà,” imọlẹ sì wà, itumọ rẹ niyẹn. Nigbati Ọlọrun ba sọ ohunkohun, ti nkan naa si farahan, itumọ ti Ọlọrun niyẹn, wipe otitọ ni Ọrọ Rẹ. Ṣe o ye yin? Nigbati O sọ pe, “Jẹ ki imọlẹ ki o wà,” iyẹn ti kọ́kọ́ wà ninu ero Rẹ ná, ki ohun ti a n pe ni imọlẹ to wà. Nigbati O sọ pe, “Jẹ ki imọlẹ ki o wà,” imọlẹ farahan ni ofuurufu, itumọ rẹ niyẹn. Ẹnikẹni ko nilo lati tumọ iyẹn, nitoripe Ọlọrun sọ bẹẹ, o si ri bẹẹ. Nigbati Ọlọrun ba sọrọ, ti o si farahan, itumọ Ọrọ Rẹ niyẹn. Eeṣe ti awọn eniyan ko fi lee ri iyẹn? Kini idi ti awọn eniyan ko fi ri iyẹn?

16 Nigbati Ọlọrun ba ṣe ileri, ti Ọlọrun si sọ pe…Ni—ni atetekọṣe, ni Gẹnẹsisi, O pín Ọrọ Rẹ si iran kọọkan bi O ṣe n bọ lati ibẹrẹ titi de opin. Ni gbogbo awọn iran wọnyi, awọn ijọ ayé da awọn nkan wọnyi ru papọ nipa àṣà, ati bẹẹ bẹẹ lọ, Ọlọrun si maa n rán awọn wolii wá, ni Majẹmu Laelae ati Titun! Ọrọ Oluwa si maa n tọ wolii wá. Bawo ni Ó ti n ṣe e? O n fi Ọrọ Ọlọrun han. Ifihan Ọlọrun yoo sọ boya o tọ́ tabi kò tọ́. Ẹnikẹni ko nilo lati tumọ Rẹ, Ọrọ naa ni o n tumọ ara Rẹ. Ọlọrun ṣe ileri rẹ, o sì ṣẹlẹ!

17 Rere wo ni yoo ṣe lati tun ṣọ nkan miiran nipa Rẹ? Eniyan ẹlẹṣẹ wo ni yoo gbiyanju lati ṣọ (nigbati Ọlọrun ba ṣe ileri ti O si mu u ṣẹ) wipe iyẹn kuna? Ọlọrun funra Rẹ ni o n ṣe Itumọ ara Rẹ, O n ṣe itumọ. Ko nilo ẹnikẹni lati tumọ Oun, Oun ni o n tumọ ara Rẹ nipa fifi ohun ti O ṣe ileri wipe Oun yoo ṣe han.

18 Ah, ijọ iba lee ri iyẹn, ki wọn si ri ileri ti a pin fun iran kọọkan! Gbogbo awọn iran yooku, Ọlọrun n ranṣẹ wá (ni gbogbo igba ijọ mejeeje pẹlu) O si ti fi ohun gbogbo ti O ṣe ileri lati ṣe hàn. Ohun gbogbo ni, ko si ohun kan ti O fi silẹ laiṣe. Bẹẹ gan-an ni. Ohun ti O ṣọ wipe Oun yoo ṣe, oun naa ni O ṣe.

19 Nitori nigbati Ọlọrun ṣọ ni Isaiah, O ni, “Wundia kan yoo loyun,” o si loyun. Njẹ, tani—tani o lee tumọ iyẹn? Ọlọrun ti ṣe itumọ rẹ̀. Ó ni, “Wundia kan yoo loyun,” o si loyun. Ni bayi, kini Iwọ…o kò lee… Ko si ohun kan ti a lee ṣọ nipa iyẹn, nitori Ọlọrun ṣọ wipe yoo loyun, o si loyun. Ṣugbọn oju ijọ ti fọ pupọ jù ni igbayẹn lati ri i. Wọn ni ero tiwọn nipa rẹ. O ti pọ ju—o ti yatọ pupọ ju si ohun ti wọn n reti.

20 Nibi yii, Peteru n tọka pada si i, o ni, “Ọlọrun fi Kristi hàn nipasẹ Ọrọ Rẹ, O ni, ‘Eyi ni ayanfẹ Ọmọ Mi.’” Awọn onigbagbọ wọnyi wa nibẹ. Kristi si ni ifarahan Ọlọrun. O maa n fi Kristi han nigbagbogbo nipasẹ Ọrọ Rẹ, nitoripe Kristi ni Ọrọ naa. O n fihan nigbagbogbo.

21 Nigbati Ó ṣọ…Ni ọjọ Noah, Kristi wà ninu Noah. Ṣe ẹ gba iyẹn gbọ? Noah ṣọ pe, “Òjò yoo rọ̀. Òjò yoo rọ̀, a o pa aye run.” Ojo rọ. Iyẹn ko nilo itumọ kankan. Ojo rọ, nitoripe Ọlọrun ninu Noah, ṣọ pe, “Ojo yoo rọ.” Wolii ni oun, ẹri rẹ si ni wipe ohun ti o ṣọ wa si imuṣẹ. Nitorinaa, wọn ko nilo lati tumọ iyẹn.

22 Awọn kan ti o wà nibẹ lee ṣọ pe, “Ọkunrin yii ko mọ ohun ti o n ṣọ.”

23 Ṣugbọn Ọlọrun ti maa n ṣe ileri nigbagbogbo pe, “Ti ẹnikan ba wà laarin yin ti o jẹ ẹni ẹmi, tabi wolii, ti ohun ti o n ṣọ si n wa si imuṣẹ, ẹ gbọ tirẹ.” Bẹẹ ni, nitoripe otitọ ni. O gbọ́dọ bá Ọrọ naa mu. Noah si wà ni ibamu pẹlu Ọrọ naa. Nigbati o ṣọtẹlẹ wipe ojo yoo rọ, ojo si rọ. Iyẹn ko nilo itumọ kankan, nitoripe o ṣẹ bẹẹ gẹ́lẹ́.

24 Isaiah ṣọ pe, “Wundia kan yoo loyun,” o si loyun. Iyẹn ṣajeji pupọ. Nitoripe lẹyin ọpọlọpọ ọgọọgọrun ọdun ni wundia naa to loyun.

25 O ṣajeji tobẹẹ ti eniyan rere kan ti orukọ rẹ n jẹ Josẹfu, ọkọ rẹ, “ti o jẹ olododo eniyan, ti ko si fẹ doju ti i ni gbangba…” Ọkunrin rere yẹn, ni igba yẹn, bawo ni yoo ti ri lara Josẹfu nigbati o fẹ Maria ṣọna.

26 A fẹ ẹ ṣọna. Ni igba yẹn, lati yẹ iyẹn, o jẹ nkankan naa pẹlu ṣiṣe panṣaga. Ẹwẹ, sí Josẹfu, o dabi ẹni wipe Maria fẹ fi oun bojú ni, tabi

lati fi oun boju fun aṣiṣe rẹ̀, nitori oun ni o ti loyun yii, lai tii ṣe igbeyawo, a fẹ ẹ ṣọna lasan ni. Iru ọgbọn bẹyẹn, wọn yoo ṣọ ọ ni okuta pa ni; o nilati ri bẹẹ, gẹgẹbi ofin.

27 Josẹfu, ọkọ rẹ̀, olododo eniyan ni, olododo eniyan gidigidi ni. O gba Ọlọrun gbọ. Nigbati o ba si wo o pẹlu oju ifẹ ti o tobi, ti o si rò yẹn, ti yoo wipe, “Josẹfu, Angẹli Agba Gabrieli bẹ mi wò, o si ṣọ fun mi pe emi yoo loyun, lai mọ ọkunrin kankan.”

28 Iba ṣe wipe Josẹfu wo inu Iwe Mimọ ni, wolii yẹn ṣọ wipe yoo ṣe bẹẹ! Ọlọrun ni O n tumọ Ọrọ ara Rẹ! Ṣe ẹ ri i? Ṣugbọn o ti ṣàjèjì jù.

29 Ohun ti o maa n ṣẹlẹ ni gbogbo iran niyẹn. Ọrọ Ọlọrun ṣajeji si awọn eniyan; O ti ṣajeji jù. Ọlọrun maa n sabaa ṣe ohun ajeji. Ibikibi ti Ọlọrun ba wa maa n ṣajeji. O lodi si ilana aye, nitoripe awọn ti ni awon nkan, bi wọn se rò wipe ó yẹ ki ó rí. Ṣugbọn Ọlọrun yoo wá, yoo si ṣe ohun ajeji.

30 “Bawo ni wundia yii yoo ṣe loyun?” Oun jẹ olootọ, o si wa oju Ọlọrun nitori rẹ.

31 Ọlọrun si ba a sọrọ loju àlá, wipe, “Josẹfu, Iwọ ọmọ Dafidi, maṣe bẹru lati mu Maria aya rẹ sọ́dọ̀, nitori eyi ti o yún ninu rẹ, lati ọwọ Ẹmi Mimọ wá ni. Ọlọrun ti ràdọ̀ bo o. Ohun ti o fa a niyẹn.”

32 Njẹ ẹ kiyesi bi Ọlọrun ṣe bá Josẹfu lò nibẹyẹn? Ni ọna miiran, ni ọna àlá. A mọ wipe awọn ala wà, a gbagbọ ninu awọn ala. Emi gbagbọ ninu awọn ala. O ṣẹlẹ wipe…Ọlọrun ti maa n ba awọn eniyan lo nipa ala. Ṣugbọn ọna miiran ni ala jẹ, o ṣee ṣe ki o jẹ otitọ tabi irọ, ayafi ti a ba tumọ rẹ. Ṣugbọn oun kò nilo itumọ kankan. Ọlọrun funra Rẹ ni o n ba Josẹfu sọrọ tààrà, nitori ko si wolii ni ilẹ naa nigbanaa lati ṣe itumọ. Fun irinwo ọdun ni wọn ko fi ni wolii kankan. Nitorinaa, ọna miiran ti o tun dara ju, ti Ọlọrun fi bikita fun itọju, itọju Ọmọ Oun funra Rẹ, ni ki O ba Josẹfu sọrọ nipasẹ ala, lai nilo itumọ. O ni, “Otitọ ni obinrin naa sọ. Ohun Mimọ nnì ti o yun ninu rẹ̀, Ọmọ Ọlọrun ni.” Ko nilo itumọ kankan.

33 Ọlọrun maa n tumọ ara Rẹ fun awọn olootọ ọkan. Awọn ọkunrin ati obinrin ti wọn n wo—awọn nkan ti o ru ni loju, ti o ba jẹ olootọ ati olododo, ti o si gbagbọ, Ọlọrun ni ọna ti yoo gba tumọ rẹ̀ fun ọ. Lakọkọ, wadi ti o ba jẹ ileri. Iba ṣe wipe Josẹfu pada lọ ni, ki o kuro ninu àṣà, ki o pada sinu Bibeli, ki ó ṣe iwadi, Isaiah sọ pe yoo ṣe nkan yẹn.

34 Awọn ohun ti a sọrọ nipa Rẹ, ati ibi Rẹ, ati ohun gbogbo nipa rẹ ni Iwe Mimọ sọ, “lati ẹnu awọn wolii Mimọ,” gẹgẹbi Peteru ṣe sọ. Ko si ẹnikẹni ti o ni ètò lati fi itumọ ikọ̀ọ̀kọ̀ si iyẹn. Ohun ti Ọlọrun sọ wipe yoo ṣẹlẹ ni. Oun ni ifarahan Ọrọ Ọlọrun ti a ṣe ileri fun ọjọ yẹn. Ọlọrun sọ bẹẹ, o si ri bẹẹ. O pari.

35 Jesu sọ…Nigbati O wà lori ilẹ aye, nigbati iṣẹ-iriju iwaasu Rẹ kò yé wọn, o ti lagbara ju, o jẹ iyanu pupọ ju, (wọn ko lee), o jẹ iyanu pupọ ju, ni mo fẹ sọ. Ọrọ Rẹ ko ye wọn. O ni, “Ẹ wá inu Iwe Mimọ!” (Mo lero wipe n ko pariwo si yin leti ju nibẹyẹn, bi mo ṣe n sọrọ sinu iyẹn.) “Ẹ wá inu Iwe Mimọ, nitori ninu wọn ni ẹ ro wipe ẹ ni Iye Ainipẹkun, Awọn ni o si n jẹri Mi.” Ṣe ẹ ri i? “Awọn ni o n sọ ẹniti Mo jẹ fun yin.”

36 Ṣe ẹ mọ, Ọlọrun pín Ọrọ naa. Ọjọ yẹn yẹ ki o jẹ ọjọ ifarahan Ọlọrun, Ọlọrun (Immanuẹli) pẹlu wa, “A o si maa pe Orukọ Rẹ ni Iyanu, Oludamọran, Ọmọ Alade Alaafia, Ọlọrun Alagbara, Baba Ayeraye. A o si pe Orukọ Rẹ ni *Immanuẹli*, ‘Ọlọrun pẹlu wa.’” Ọlọrun wa ninu Dafidi. Ọlọrun wa ninu Mose. Ọlọrun…Ọlọrun niyẹn ni gbogbo ọna, O n fi ara Rẹ hàn fun iran yẹn. Ṣugbọn ni iran yii, “Wundia kan yoo loyun, yoo si bi Ọmọkunrin kan, Oun yoo si jẹ Ọlọrun pẹlu wa.”

37 Ohun ti wọn kan-An mọ agbelebu fun niyẹn, wipe O fi ara Rẹ pe Ọlọrun, ati wipe o ru ofin Sabati. Oun ni—Oun ni Ọlọrun lori Sabati, Oun si ni Ọlọrun. Oun ki i ṣe eniyan kan lasan tabi wolii kan lasan (sibẹ Eniyan lasan ni, Wolii si ni), ṣugbọn Oun ni Ọlọrun-Wolii. Oun si ni imuṣẹ Ọrọ naa, ani ohun ti Ọlọrun sọ wipe Oun yoo ṣe gan-an. O ni, “Ewo ninu yin ni o lee da Mi lẹbi ẹṣẹ? Ẹ wá inu Iwe Mimọ! Ninu wọn ni ẹ ro pe ẹ ni Ìyè Ainipẹkun, Awọn ni o si n jẹri Mi.” Ṣugbọn nipa àṣà wọn, wọn n gbe òjìji imọlẹ iran ti o ti kọja lọ.

38 Bi mo ṣe n waasu ni ọsẹ melo kan seyin lori, “*Gbigbe ninu ojiji imọlẹ*.” Ojiji imọlẹ jẹ “ìtànṣán èké,” oorun ti o n fi itanṣan rẹ hàn, ṣugbọn ti o jẹ èké. Ojiji imọlẹ ti iran miiran jẹ itanṣan eke. Awọn eniyan maa n sabaa rin ninu ohun ti o ti ṣẹlẹ ni awọn ọdun kan seyin. Awọn ọmọ ijọ Luther n rin ninu ojiji imọlẹ Luther. Itanṣan oorun Luther dara ni ọjọ tirẹ; ti Wesley dara ni ọjọ tirẹ; ti awọn ijọ Afede-ajeji-seri-Ẹmi-Mimọ dara ni ọjọ tirẹ. A n goke si i lori àkàsọ, inu iran miiran ni a n gbe bayi! A n tẹsiwaju, siwaju, a ko lee maa pada wo ẹyin.

39 Nigbati a ba fi ẹsẹ ara wa mulẹ ninu awọn nkankan, a ro wipe a ti ṣe ohun gbogbo tan, a ti fi òté le awọn àṣà wa; iyẹn dara fun ọjọ yẹn, ṣugbọn a n tẹsiwaju! Ẹ wa inu Iwe Mimọ ki ẹ si ri ohun ti a ṣe ileri rẹ fun ọjọ oni, nigbanaa, a o mọ ibiti a wà, nigbanaa, a o lee sọ ibiti a duro si.

40 Luther; ẹ lee wo inu Iwe Mimọ ki ẹ si ri i wipe—ni iran Sardi yẹn, ẹ lee ri ohun ti a ṣe ileri rẹ gan-an. Ẹ wo iru agẹṣin ti o jade lọ, ẹ wo ohun ti o lọ pade rẹ, bẹẹ gan-an ni, “ọgbọn eniyan,” atunṣe ni. Ẹ wo Wesley, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Bi o ṣe n bọ wá si iran ijọ Afede-ajeji-seri-Ẹmi-Mimọ, ati ni gbogbo iran yẹn, ẹ wo bi o ṣe rin irin-ajo yẹn.

Ẹ wo inu Iwe Mimọ ki ẹ si ri ibiti a wà. Idi niyẹn ti Jesu fi wipe, “Ẹ wá inu Iwe Mimọ!”

41 Ẹ wo ibiti a wà! Mo gbagbọ wipe a ti wà ni ibi bíbọ̀ Ọmọ Ọlọrun lọwọlọwọ bayi. Mo gbagbọ wipe a ti wà ni iran ti—wakati ti Ó lee farahan nigbakuugba. Mo gbagbọ wipe Iwe Mimọ sọ bẹẹ, wipe a ti wa ni igba wakati ikẹyin fun itan aye yii. Mo le ri i bi awọn nkan ṣe n ṣẹlẹ. Ẹ wo Agbajọpọ Ijọ Agbaye ti o n dari gbogbo ijọ lọ sinu rẹ, sinu àmì ẹranko naa. Ẹ wo Ijọba Roomu ati ohun ti o n ṣe, ati gbogbo awọn yooku. Ẹ ri bi wọn ṣe n ko ara wọn jọ, ti wọn tilẹkun mọ́ Imọlẹ si ita, ti wọn tilẹkun mọ Ihinrere si ita. Gbogbo eniyan nilati darapọ mọ wọn, ki ẹ si rin inu imọlẹ wọn, aijẹbẹẹ, ẹ ki yoo rin rara. Ẹ wo o, a ti wà ni igba ikẹyin. Ko si ohun ti o ṣẹku fun wa bikoṣe ki a di Ọlọrun mu, ki a si gba Ọrọ Rẹ gbọ. Ọrọ yẹn tọ́nà ni gbogbo igba.

42 Ni igba ijọ Laodikea, igba ijọ yẹn nikan, ninu gbogbo wọn, ni wọn ti ti Kristi jade kuro ninu ijọ. Oun wa ni ita, O n kanlẹkun. Ki lo ṣẹlẹ? Agbajọpọ Ijọ Agbaye yii ni yoo ti I sita. Bibeli sọ wipe Oun yoo wa ni ita, O si wà nibẹ. Kini o ti jade? Ọrọ naa ni. Oun si ni Ọrọ naa, Oun ni Ọrọ naa nigbagbogbo, Oun si ni Ọrọ naa sibẹ ni aṣalẹ yii! Oun ni Ọrọ naa.

43 Bibeli wipe, “Ọrọ naa mú, O si lagbara ju idakida oloju meji lọ,” Heberu ori kẹrin, “olumọ èrò inú ati ète ọkan.” Ohun ti Ọrọ naa jẹ niyẹn! O yẹ ki wọn ti mọ ẹniti O jẹ nigbati Jesu sọ bẹẹ ni ọjọ yẹn.

44 Ẹ kiyesi ohun ti O ṣe. Lọjọ kan, O duro sibẹ, ni ibẹrẹ iṣẹ-iriju iwaasu Rẹ. Ọkunrin kan tọ Ọ wá, ti Orukọ rẹ n jẹ Simoni, Simoni Peteru. Nigbati Peteru wo O—ti o si ri I, Jesu wi fun-un pe, “Simoni ni Orukọ rẹ, ọmọ Jona si ni ọ.” (O yẹ ki o ti mọ wipe Mose sọ pe, “Oluwa Ọlọrun yin yoo gbe wolii kan dide bii temi, ẹ si gbọdọ gbọ Tirẹ.”) Ọkunrin kan si niyi, ti ko ri i ri ni gbogbo ọjọ aye rẹ, O ni “Simoni ni Orukọ rẹ, ọmọ Jona si ni ọ.” Ki lo ṣẹlẹ, o mọ lẹsẹkẹsẹ wipe iyẹn ko lee jẹ ẹlomiran…Irinwo ọdun ni wọn ko fi ni wolii, Ọkunrin kan si niyi ti o n sọ ẹniti o jẹ fun-un. Abajọ ti o fi lee gba a!

45 Filipi lọ ni igba yẹn, o lọ wa—o ri Nataniẹli labẹ igi kan, o si mu u pada tọ Jesu wá. Jesu wipe, “Wo o, ọmọ Israẹli, ninu ẹniti ko si ẹtan.”

O ni, “Rabbi, nigbawo ni O mọ mi?”

46 O ni, “Ki Filipi to pe ọ, nigbati o wa labẹ igi, Mo ti ri ọ.”

47 O ni, “Rabbi, Iwọ ni Ọmọ Ọlọrun! Iwọ ni Ọba Israẹli.” O mọ wipe Iyẹn jẹ Kini? Ko nilo itumọ kankan, Jehofa ni o sọ Iyẹn!

48 Awọn kan duro sibẹ ti wọn ko gba a gbọ. Wọn ni, “Beelsebuubu ni Ọkunrin yii. O ni—O ni ọgbọn kan ti O n ta. O jẹ—alafọṣẹ ni, tabi nkankan.”

49 Jesu wo wọn, O ni, “Kini, ti ẹ ba sọ ọrọ odi yẹn si Ọmọ Eniyan, a o dari rẹ ji yin. Ṣugbọn nigbati Ẹmi Mimọ ba de, ti O si n ṣe nkan kannaa, ti ẹ ba sọ ọrọ odi si Iyẹn, a ki yoo dari rẹ ji yin laelae, ni aye yii tabi ni aye ti o n bọ.” O n sọ asọtẹlẹ nipa ọjọ tiwa, ọjọ ti awa yoo ri. Nitori ọkannaa ni Oun lana, loni, ati titi lae.

Ẹ ranti, Jesu Kristi ni o wà ninu Mose.

50 Jesu Kristi ni o wa ninu Dafidi. Nigbati Dafidi, ọmọ…Dafidi gun ori oke lọ, ọba ti a kọ́ silẹ, o sọkun lori Jerusalẹmu, Kristi ni o wà ninu rẹ yẹn. Fun bii ẹgbẹrin ọdun lẹyin iyẹn, Ọmọ Dafidi joko si Ori Oke Olifi, O boju wo Jerusalẹmu ni isalẹ, O si sọkun, O ni, “Jerusalẹmu, Jerusalẹmu, Emi yoo ha ti ràdọ́ bò ọ to, bi agbebọ adiyẹ ti n ṣe fun awọn ọmọ rẹ̀, ṣugbọn Iwọ ko fẹ!”

51 Nigbati Josẹfu wà ninu túbú, Jesu niyẹn. Nigbati a ta a fun bii ọgbọn owo-idẹ wẹwẹ, Jesu niyẹn. Nigbati a sọ ọ di igbakeji Pọtifari, Jesu niyẹn. Nigbati o joko si ọwọ ọtun Farao. Nigbati o si kuro, gbogbo eniyan…ipe dun, gbogbo eniyan si nilati wolẹ, Jesu niyẹn. Ko si ẹniti o lee de ọdọ Farao bikoṣe nipasẹ—nipasẹ Josẹfu; ko si ẹniti o lee de ọdọ Ọlọrun, bikoṣe nipasẹ Jesu. Jesu ni Ọrọ naa ti a sọtẹlẹ, ti a si mu ṣẹ, eyiti a sọ gẹgẹbi ojiji ati apẹẹrẹ.

52 Nigbati Jesu wà lori ilẹ aye, O ṣe nkan kannaa ti awọn wolii ṣe, idi niyẹn ti wọn fi mọ wipe Oun ni ifihan Ọlọrun fun Ọrọ Rẹ. Ko nilo ki a tumọ rẹ.

53 Nigbati Nataniẹli ri eleyi, ó wólẹ̀, ó wipe, “Iwọ ni Ọba Israẹli, Ọmọ Ọlọrun, Ọba Israẹli. A mọ Ọ, ko si eniyan kankan ti o lee ṣe eleyi.”

54 Nikodemu wá ni alẹ́, o sọ nkan kannaa fun awọn Farisi. Ṣugbọn njẹ ẹ mọ, wọn ti fi ara kó Agbajọpọ Ijọ wọn tobẹẹ ti wọn ko lee gba A. O fi ohun ti wọn sọ han, wipe, “Rabbi, awa…” Tani “awa”? Igbimọ wọn ni! “A mọ wipe Olukọni lati ọdọ Ọlọrun wá ni Ọ, nitori ko si eniyan ti o lee ṣe awọn nkan wọnyi bikoṣepe Ọlọrun wà pẹlu Rẹ.” Wọn da A mọ, wọn mọ wipe Oun ni, ṣugbọn wọn ti so mọ́ tiwọn.

55 Ọlọrun, ni ogoji ọdun sẹyin, ti mi orilẹ-ede yii pẹlu baptisimu Ẹmi Mimọ, awọn ọkunrin ati awọn obinrin si wà ni ita Rẹ nitoripe wọn so mọ nkan kannaa, wọn n gbe ninu ojiji imọlẹ ọjọ miran. Ki lo ṣẹlẹ? Olukuluku fẹ jẹ ọmọ-ijọ Eleto, Onitẹbọmi, Alagba, Luther, tabi nkankan. Ṣe ẹ ri i, ojiji imọlẹ lasan ni.

56 Wọn n gbe ninu ojiji imọlẹ ọjọ Mose. Kini O sọ? O ni…Wọn sọ pe, “Ọmọ-ẹyin Mose ni awa iṣe.”

57 O ni, “Iba ṣe wipe ẹ mọ Mose ni, ẹ ba mọ Mi. Mose kọwe nipa mi!”

58 Iba ṣe wipe ẹ mọ Luther ni, ẹ ba mọ iran yii! Iba ṣe wipe ẹ mọ Ijọ Eleto ni, ẹ ba mọ iran yii! Nitoripe Kristi kọwe nipa iran yii! Awọn Ọrọ naa ti a n mu ṣẹ ni a nilati mu ṣẹ ni iran yii. Ko nilo ki ẹnikẹni tumọ Rẹ, Ọlọrun ni o n tumọ ara Rẹ. Ọlọrun n tumọ ara Rẹ, nitoripe Oun nikan ni o lee tumọ Rẹ. Awọn ileri Ọlọrun maa n fi ohun ti O sọ han, itumọ rẹ si niyẹn.

59 Ni bayi, Jesu (lati ma gba àkókò), Jesu sọ, ninu iwe Johanu Mimọ, ori ikẹrinla, ẹsẹ ikejila, "Ẹniti o ba gba Mi gbọ, iṣẹ ti Emi n ṣe ni oun naa yoo ṣe pẹlu." Ṣe O sọ bẹẹ? Bẹẹni. Iyẹn ko nilo itumọ kankan. Nigbati ẹnikan ba ṣe iṣẹ yẹn, Ọlọrun niyẹn. Dajudaju!

60 O tun sọ nibẹ wipe, "Gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Lọọti, bẹẹni yoo ri nigbati Ọmọ Eniyan yoo de." Jesu ni o sọ bẹẹ. Ṣe O sọ bẹẹ? Dajudaju, O sọ bẹẹ! Iyẹn ko nilo itumọ.

Wọn ni, "Ko buru, iyẹn tumọ si…"

61 Ohun ti O sọ gan-an ni o tumọ si! "Gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Lọọti, bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ Eniyan yoo de." Ki lo ṣẹlẹ ni ọjọ Lọọti? Ẹ jẹ ki a pada seyin ni iṣẹju kan, ki a wadi ohun ti wọn n ṣe.

62 Ẹgbẹ eniyan mẹta ni o wà ni ọjọ Lọọti: onigbagbọ, alafẹnujẹ onigbagbọ, ati alaigbagbọ. Iyẹn wa laarin gbogbo apejọpọ, bakannaa ni.

A ri i wipe awọn ara Sodomu ni alaigbagbọ.

Lọọti ni alafenujẹ onigbagbọ.

63 Abrahamu ni onigbagbọ. Oun ni ẹniti a fidi majẹmu naa mulẹ fun. Oun ni ẹniti n foju sọna fun ọmọ ileri. Oun ni ẹniti o n reti rẹ. Amin. (Emi ko ṣe "amin" si ara mi. *Amin* tumọ si "Bẹẹni ki o ri!") Otitọ si ni. Abrahamu ko si ni Sodomu. Abrahamu wa ni ẹyin odi Sodomu. Oun jẹ apẹẹrẹ Ijọ ẹmi loni.

64 Lọọti jẹ apẹẹrẹ ijọ ẹlẹkọ-adamọ ti o ṣì wà ni Sodomu sibẹ. Ẹ kiyesi i, Bibeli sọ pe, "Ẹ̀ṣẹ̀ Sodomu n ba ọkan ododo rẹ jẹ lojoojumọ." Kini ṣe ti ko ni agbara to lati tako o? Ọpọlọpọ awọn eniyan rere ni o joko sinu ijọ loni, wọn n wo ita, wọn si n ri awọn obinrin pẹlu ṣokoto pénpé ati awọn ọkunrin ti o n ṣe nkan wọnyi, ti awọn ọmọ-ijọ wọn si n lọ sibẹ, ti wọn n ṣeré lori papa ni Ọjọ Isimi, ti wọn n jẹ àṣè, ti wọn n luwẹ ati awọn nkan bẹẹ, dipo ki wọn lọ sinu ile-ijọsin. Wọn yoo joko sile ni alẹ Ọjọru, wọn yoo maa wo tẹlifiṣan, dipo ki wọn lọ si ile-ijọsin. O wu wọn lati sọ nkankan nipa rẹ, ṣugbọn igbimọ ijọ yoo le wọn jade. Ki lo ṣẹlẹ? Lọọti tun ni, ti o n wo ita lati oju ferese rẹ, ti o si n ri ẹṣẹ, ṣugbọn ẹru n ba a lati pe ẹṣẹ ni "ẹṣẹ"!

65 Abrahamu ko si ninu ibajẹ wọn, ita rẹ ni o wà. Oun jẹ apẹẹrẹ Ijọ ẹ̀mí. Ẹ kiyesi ohun ti o ṣẹlẹ ni igba ikẹyin, ki ina to rọ bi ojo. Keferi

si ni awọn yẹn. O n ṣe apẹẹrẹ wipe ina yoo rọ bi ojo sori aye Keferi loni, nigbati a o tú awọn ijọba ká, ti a o si da ina sun wọn. “Awọn Ọrun yoo jona,” ni Oluwa wi, “wọn yoo ti inu ooru gbigbona gidigidi di yiyọ.” Ojiji rẹ lasan ni iyẹn.

66 Ẹ jẹ ki a wo wọn bayi. Abrahamu ti wa ni ita, ko si ninu Sodomu, o wa ni ita Sodomu. Lọọti wa ninu Sodomu sibẹ.

67 Ohun ajeji kan ṣẹlẹ, ni owuro ọjọ kan ti ooru mu, o nilati jẹ nkan bii agogo mọkanla owuro, o ri awọn ọkunrin mẹta ti wọn n bọ, eniyan lasan ni wọn, wọn n rin bọ loju ọna, ọna ẹlẹsẹ̀. Abrahamu joko sabẹ igi oaku, o n simi. O ti jade lọ tẹ̀lẹ̀, boya o tèlé agbo ẹran jade ni owuro ọjọ yẹn, o ṣèṣẹ̀ wọle, ni nkan bii ọwọ ọsan. O si ri awọn ọkunrin mẹta ti wọn n bọ. Nkankan wà nipa awọn ọkunrin wọnyẹn, ti o jẹ wipe, ó mọ̀. Akiika!

68 Nkankan maa n wà nipa Ọlọrun, nigbati Ó ba wá si aarin awọn eniyan, wọn maa n mọ Ọ́. Wọn mọ̀ Ọ́. Nkankan maa n sọ fun wọn wipe, ifidimulẹ kan wa nibẹ.

69 Abrahamu sare, o ni, “Oluwa mi, wa, jẹ ki n bu omi diẹ, ki n bu u, ki O si wẹ ẹsẹ̀ Rẹ, ki n si fun Ọ ni okele ounjẹ kan, lẹyinnaa, Ẹ lee maa ba ọna Yin lọ.” Nitorinaa, O yà sibẹ. Oun sare lọ si aarin agbo ẹran, o mu ọmọ aguntan kan, o si pa a, o ni ki iranṣẹ kan kun-ún. O lọ sinu àgọ́ ni isalẹ, o ni ki Sarah po iyẹfun diẹ, ki o se, ki o se ounjẹ diẹ, ki o se burẹdi diẹ, ki o si se akara ni ori ààrò. O ko wọn jade, o si gbe e siwaju wọn. Bi wọn ṣe joko sibẹ, ti wọn n jẹun, wọn bẹrẹsi ṣe akiyesi, Ọkunrin yii ṣaa n wo ọna Sodomu ṣaa. O si wipe…

70 Ṣe ẹ ranti, meji ninu wọn lọ si Sodomu. Awọn meji lọ si Sodomu. Ẹ jọwọ ẹ maṣe padanu eleyi. Mo n tọka si ohun ti Jesu sọ. Meji ninu wọn lọ si Sodomu lati mu Lọọti jade ati awọn ti o ṣetan lati jade kuro nibẹ. Awọn meji ti o lọ sibẹ, wọn lọ sibẹ lọ waasu ni. (Ọkan ninu wọn duro ti Abrahamu. Ẹ kiyesi iṣẹ-àmì ti Ó ṣe). Wọn ni àmì kan nibẹ, o wa…a bu ifọju lu awọn ara Sodomu. Wiwaasu Ihinrere maa n fọ alaigbagbọ loju nigbagbogbo ni. Ẹ kiyesi ohun ti o ṣe e.

71 Ọkan duro sẹyin nibi, O si ṣe iṣẹ-ami kan niwaju Abrahamu.

72 Njẹ ẹ tilẹ kiyesi i? Gbogbo ònkọ̀tàn, ẹ wo inu Iwe Mimọ, ẹ wo ìtàn, ko si igba kankan ninu igba ijọ, nibiti ẹnikan ti lọ sọdọ awọn ijọ-ara ti o wa ninu aye, ni aarin awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ, ko si ẹnikankan ti Orukọ rẹ pari bii ti Abrahamu, h-a-m, ri. Ṣugbọn loni, wọn ti ni ẹnikan, G-r-a-h-a-m. Bẹẹ ni. O sọkalẹ lọ sibẹ, o n pe wọn jade. Iṣẹ nla ni o n ṣe. Graham, Billy Graham, iranṣẹ Ọlọrun laarin awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ, awọn oloṣelu, ati bẹẹ bẹẹ lọ, o n ba wọn wi.

73 Nijelo, nigbati wọn fẹ ki o dije fun ipo Aarẹ, o kọ̀ jálẹ̀. Ki Ọlọrun bukun fun-un nitori iyẹn. Kódà, awọn ile-iṣẹ ọti yẹn, wọn kò tilẹ ni jẹ

ki o pari ìgbésẹ akọkọ. Wọn ìbá na ọpọlọpọ biliọnu owo dọla, nitoripe oun ìbá le wọn jade, awọn ile-iṣẹ siga ati iru awọn nkan bẹẹ. Oun wa nibẹ gẹgẹbi iranṣẹ Ọlọrun si awọn ara Sodomu. Bẹẹ ni.

74 Ṣugbọn ẹ ranti, Ẹnikan wà ti o duro ti Abrahamu, Ọkunrin miiran, ki i ṣe awọn meji ti o sọkalẹ lọ si ibẹyẹn, gẹgẹbi ajihinrere ode oni ti o sọkalẹ lọ si ibẹyẹn lati waasu. Ẹ kiyesi, Ẹnikan wà ti o duro sibẹyẹn. Awọn meji gba ọna *yẹn* lọ, Ẹnikan duro *nibi* ti Abrahamu. Ẹniti o duro ti Abrahamu fun-un ni àmì kan.

75 Ẹ kiyesi i bayi, "Abram" ni orukọ rẹ tẹlẹ, "Sarai" si ni iyawo rẹ tẹlẹ. Ọjọ kan tabi meji ṣaaju iyẹn, Ọlọrun fi ara han-an, O si wi fun-un pe, "Mo fẹ yi orukọ rẹ pada bayi, lati Abramu si Abrahamu." (Ṣe ẹ ri i, G-r-a-h-a-m jẹ lẹta mẹfa, eniyan niyẹn). Ṣugbọn A-b-r-a-h-a-m jẹ meje, lẹta meje; h-a-m, o pari pẹlu h-a-m.

76 Ẹwẹ, ninu Ijọ ẹmi, Ẹnikan wa pẹlu Abrahamu nibẹ, ẹ si kiyesi ohun ti Ó sọ. O ni, "Abrahamu," (ki i ṣe "Abramu") "Abrahamu, nibo ni iyawo rẹ" (ki i ṣe "S-a-r-r-a") "S-a-r-a-h wa? Nibo ni iyawo rẹ Sarah wa?"

77 Ẹ kiyesi ohun ti o sọ, "O wa ninu agọ lẹyin Rẹ."

78 O si wipe, "Emi yoo bẹ yín wò. Emi yoo bẹ yín wò." Ṣe ẹ ri èdè aladori ẹnikan ti o wa nibẹyẹn, Ẹni naa, ni ibamu pẹlu ileri ti O ti ṣe. Ọlọrun niyẹn! O ni, "Emi yoo bẹ yín wò."

79 Sarah ẹ̀wẹ̀, (ni ọna ti yoo gba ye gbogbo wa) rẹrin ìkòòkò, sinu ara rẹ, o wipe, "Emi, iya arugbo, oluwa mi naa, ọmọ ọgọrun ọdun" (iyẹn Abrahamu) "oun naa ti di arugbo, a ti kuro ni ọdọ." O ni, "Kini, awa ko lee jẹ igbadun bi iyẹn mọ, emi ti di arugbo, oun naa si ti di arugbo." O tun wipe, "Awa ko lee ṣe iyẹn." O ni, "Bawo? Awọn nkan wọnyi ko lee ṣẹlẹ!"

80 Ẹni naa—Ọkunrin naa (Ọlọrun ninu ẹran-ara eniyan) wipe, "Eeṣe ti Sarah fi rẹrin ti o si ṣiyemeji, ti o si n sọ awọn nkan wọnyi?" Ninu agọ, lẹyin Rẹ.

81 Ẹ kiyesi i bayi, njẹ iru iṣẹ-iriju ti Jesu Kristi ni kọ niyẹn! O wo ijọ eniyan, O si mọ ero ọkan wọn. O sọ ẹniti Peteru jẹ fun-un, ati orukọ baba rẹ. O sọ fun Natanieli.

82 O sọ fun obinrin eti kanga, nigbati o sọ pe…O ni, "Lọ bu omi fun Mi wa," tabi, "Fun Mi ni omi mu."

83 Oun sọ pe, "Alagba, ko ba àṣà mu wipe ki Iwọ maa sọrọ pẹlu… ki ẹyin Juu maa ba ara Samaria sọrọ. A ko ni ohunkohun lati jọ ṣe papọ."

84 O ni, “Ṣugbọn iba ṣe wipe o mọ Ẹniti Iwọ n ba sọrọ ni, Iwọ iba beere omi lọwọ Mi.” Ijiroro naa n tẹsiwaju. O ni, “Lọ pe ọkọ rẹ wa ki ẹ si maa bọ nihin.”

O ni, “Emi ko ni ọkọ.”

O ni, “Otitọ ni o sọ, nitoripe o ti ni marun seyin.”

O ni, “Alagba!”

85 Ẹ wo iyatọ ti o wa laarin iyẹn ati awọn—awọn alufaa igba yẹn, igbimọ ti o n gbe ninu ojiji imọlẹ ọjọ miiran. Wọn ni, “Eṣu ni eleyi!” Wọn nilati sọ nkankan fun ijọ wọn, nitoripe ohun ti o gba niyẹn.

86 Ṣugbọn kini obinrin yii, ẹniti Irugbin iyantẹlẹ wa ninu ọkan rẹ… Gbogbo nkan wọnyẹn ti ṣú u, o ti jade si igboro gẹgẹbi aṣẹ́wó. Ṣugbọn nigbati o ri Iyẹn, o ni, “Alagba, mo woye wipe Wolii ni Ọ. A koi tii ni ọ̀kan fun irinwo ọdun seyin, wọn si sọ fun wa wipe nigbati Messiah ba de, awọn nkan ti yoo ṣe naa niyẹn.” Akiika! Irugbin ti o wà nibẹ soji! Kini idi? Ko nilo itumọ.

87 Jesu wipe, “Emi ni Ẹni naa ti o n ba ọ sọrọ.” Iyẹn ko nilo a n tumọ rẹ. O ti ṣe iṣẹ-iyanu, O si ti jẹri wipe Oun ni Messiah naa, amin, O jẹri si ohun ti Ọlọrun ti ṣe ileri (“Oluwa Ọlọrun rẹ yoo gbe Wolii kan dide laarin yin bii emi,” ni Mose sọ). Kini? Ifidimulẹ Iwe-Mimọ ni!

88 O sare lọ saarin ilu, o ni, “Ẹ wa wo Ọkunrin kan, Ẹniti o sọ ohun gbogbo ti mo ti ṣe fun mi. Njẹ Kristi naa ha kọ eyi? Oun ha kọ niyi? O sọ ohun ti mo ti ṣe fun mi.”

89 Ni bayi, ẹ kiyesi i, Jesu, Oun ni O wà ninu Ọkunrin yẹn ti o kọ èyìn Rẹ si Àgọ́, ti O si sọ ohun ti Sarah n ronu nipa rẹ ninu àgọ́.

90 Ọrọ Ọlọrun sọ, ninu iwe Heberu, ori kẹrin, wipe…O sọ bayi, “Ọrọ Ọlọrun lagbara, O si mu ju idakida oloju meji, o n gun ni, ani titi de pínpín ọkan ati ẹmi níyà, ati orike ati ỳrá inu egungun, oun si ni olùmọ̀ èrò inu ati ète ọkàn.” Ọrọ yẹn ni! Gbogbo igba ti wolii kan ba wá, o maa n wá pẹlu Ọrọ naa. Oun si ni Ọrọ naa fun iran yẹn. Kini O si ṣe? Alasọtẹlẹ ti O n mọ ero ti o wa ninu ọkan.

91 O ṣe e ninu Jesu Kristi nitoripe Oun ni ẹkunrẹrẹ Ọrọ naa.

92 Jesu si wipe, “Gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Sodomu, bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de.” Ẹmi Ọlọrun yoo wá sori ilẹ aye ni ìrí eniyan, Ọlọrun ti Ó farahan ninu ẹran-ara eniyan (Amin! Ṣe o ye yin?), yoo si ṣe nkan kannaa ti Ọlọrun ṣe ninu ẹran-ara eniyan ni Sodomu. Ẹ ranti, wọn n duro de ọmọ ileri kan. Kete lẹyin iyẹn, ọmọ ileri naa de. Ami ti o kẹyin niyẹn ti Sodomu, ani ẹgbẹ Abrahamu ri ki ọmọ ileri naa to de. Njẹ ẹ kiyesi iyẹn? Ni bayi, Ijọ ẹmi ti de wakati yẹn.

93 Ẹnikan sọ pe, “Arakunrin Branham, njẹ o sọ wipe ‘Ọlọrun niyẹn bi’?”

94 Bibeli sọ wipe Ọlọrun ni! Ko nilo itumọ. Oun ni Ẹlohimu. Ohun ti Abrahamu pe E niyẹn. Gbogbo ẹniti o ba n ka Bibeli mọ bẹẹ. *Ẹlohimu*, “Ẹni ti O dánìkan tó tán.” Oun ni Akọkọ, ati Ikẹyin; Ibẹrẹ, ati Opin. Ẹlohimu! Abrahamu pe E ni “Ẹlohimu.” *Ọlọrun*, pẹlu lẹta nla, ni ede Heberu, *Ẹlohimu*; bii wipe, “Ni atetekọṣẹ, Ọlọrun,” Ẹlohimu.

95 Oun ni Ẹlohimu ti O farahan ninu ẹran-ara eniyan, ti O n wọ aṣọ eniyan, ti O n jẹ ounjẹ eniyan. Amin! Àmì nikẹyin ọjọ, wipe Ọlọrun yoo tun farahan laarin awọn eniyan Rẹ ninu ẹran-ara eniyan! Amin! Jesu wipe, “Iṣẹ ti Mo ṣe ni ẹyin naa yoo ṣe pẹlu. Gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Sodomu, bẹẹni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de.” Amin! Iyẹn ko nilo itumọ; ifarahan ni o nilo, ohun ti o nilo niyẹn. Amin. Ṣe ẹ gba iyẹn gbọ?

Ẹ jẹ ki a tẹri wa ba.

96 Baba wa Ọrun, a fi ileri Rẹ fun Ọ ni aṣalẹ yii, wipe Iwọ ni o sọ awọn nkan wọnyi. Iwọ ni o ṣe ileri wọn. Ko si ẹnikan ti o lee mu ki Ọrọ Rẹ yè bikoṣe Iwọ. Iwọ wipe, “Jẹ ki imọlẹ ki o wà,” imọlẹ si wà. Ẹnikẹni ko nilo lati tumọ iyẹn, o farahan.

97 Gẹgẹbi a ṣe tun ohun ti Isaiah sọ, iyẹn wolii yẹn, wipe, “Wundia kan yoo loyun,” o si loyun; ko nilo ifarahan, o ṣe bẹẹ. Ohun ti o ṣẹlẹ niyẹn.

98 O sọ pe, nigbati Ó ba de, a o bi I ni Bẹtlẹhẹmu, “Lati Bẹtlẹhẹmu, Judea. Iwọ ko ha kere julọ laarin awọn ọmọ alade Judah, ti Israẹli? Ṣugbọn lati inu rẹ ni Oluṣakoso awọn eniyan Mi yoo ti jade wa.”

99 Awọn ohun ti Oun yoo ṣe, Ọrọ ti Oun yoo sọ lori agbelebu, bi a o ṣe da A lẹbi, ti a o kan èsò mọ ẹsẹ Rẹ ati ọwọ Rẹ; “A ṣa A logbẹ nitori irekọja wa, a pa A lara nitori aisedeedee wa; ina alaafia wa n bẹ lara Rẹ; ati nipa ina Rẹ ni a fi mu wa lara da.”

100 Gẹgẹbi Dafidi ti sọ, “Emi ki yoo fi ọkan Rẹ silẹ ni ipo oku, bẹẹni Emi ki yoo jẹ ki Ẹni Mimọ Mi ri idibajẹ.” Ni ọjọ kẹta, ki wakati mejilelaadọrin to pé lati mu ki ara Rẹ dibajẹ, Ọrọ Ọlọrun sọ pe, “Oun yoo jinde.” (Wọn sọ pe wọn ji ara Rẹ gbe lọ ni; wọn ṣì gba iyẹn gbọ sibẹ.) Ṣugbọn awa gba Ọrọ Rẹ gbọ, Oluwa! Ó farahan. Jesu Kristi jinde, O si wipe, “Emi yoo…Kiyesi i, Emi wa pẹlu yin nigbagbogbo, ani titi de opin aye.”

101 Awa gbagbọ wipe O wa nibi ni aṣalẹ yii. Awa gbagbọ wipe Iwọ ni Jesu Kristi kannaa ni aṣalẹ yii, nibi yii, gẹgẹbi O ṣe ri tẹlẹ. Iwọ kan n wa awọn oju ni, awọn ọwọ, awọn ẹsẹ, ẹnu, ọkan, awọn ara, ti Iwọ lee lo lati fi ara Rẹ han. Ọlọrun, ya wa si mimọ ni aṣalẹ yii, ki a lee ri Jesu Kristi alaaye, ki O maa gbe laarin wa. Jẹ ki Ó wá! Nigbanaa

ni yoo ṣẹ, gẹgẹbi ebi ti o n pa awọn ara Gíríkì ti o wa ni ọjọ yẹn, ti wọn wipe, “Alagba, awa n fẹ ri Jesu.” Wọn si ri I. Inu wọn yoo ha ti dun to nigbati wọn ri I!

102 Ọlọrun, ọkannaa ni Ọ loni. O si ṣe ileri wipe, bi awa ba pebi, awa lee ri Ọ. “Nigba diẹ si i, aye ki yoo ri Mi” (iyẹn alaigbagbọ); “ṣugbọn ẹyin yoo ri Mi, nitori Emi yoo wa pẹlu yin, ani ninu yin, titi de opin aye.” Awa mọ wipe Iwọ jẹ ọkannaa lana, loni, ati titi lae.

103 Oluwa, a ti sọ Ọrọ naa, a ti kọ Ọ́, ni bayi, jẹ ki o ṣẹ, fun Ogo Ọlọrun, lati fihan wipe O n mu Ọrọ Rẹ ṣẹ. Amin. Ki Ọlọrun bukun fun yin.

104 Emi yoo pe ila adura. Mo gbagbọ wipe Billy sọ pe oun pin awọn kaadi adura, lati oókan de ọgọrun, tabi- nkankan bẹyẹn. Kò sí nibi nisisiyi. Ṣe…Kini nọ́mbà kaadi adura…Ki ẹnikan wo ẹyin tirẹ… Yoo—yoo jẹ nọmba kan ati—ati lẹta kan. (A, B, C, D, tabi…). Kini, A? O dara.

105 Ẹ jẹ ki a pe A, nọmba kinni, ekeji, ẹkẹta, ẹkẹrin, ẹkarun. Ẹ maa dide duro bayi. A, nọmba kinni, nọmba keji, nọmba kẹta, nọmba kẹrin. Ikẹrin, emi ko ri i ki o dide. Kaadi adura kẹrin. Eni, eji, ẹta. Adura…Boya ẹni yẹn ko lee dide. Ti ko ba lee dide, ki ẹnikan wo kaadi ẹniti o wa lẹgbẹ rẹ, o ṣee ṣe ki o ni kaadi, ṣugbọn ki o ma lee dide. Ni kiakia bayi. Oun niyẹn, ẹrin. Àrún, kaadi adura karun. Ẹfa, eje, ẹjọ, ẹsan, ẹwa, mọkanla, mejila. Ẹ maa bọ wa soke bayi bi a ṣe n pe nọmba yin. Nọmba kinni, eji, ẹta, ẹ maa gba ibi yii bọ. Kaadi adura kinni, ikeji, ikẹta, ikẹrin, ikarun, ikẹfa, ikeje, ikẹjọ, ikẹsan, ikẹwa, ikọkanla, ẹ duro si aaye yin. Ikọkanla, ikejila, ikẹtala, ikẹrinla, ikẹẹdogun, ikẹrindinlogun, ikẹtadinlogun, ikejidinlogun, ikọkandinlogun, ogun, ikọkanlelogun, ikejilelogun, ikẹtalelogun, ikẹrinlelogun, ikarundinlọgbọn. Bi ẹnikẹni ba wà ti ko lee…

106 Mo ri ọdọmọkunrin kan ninu kẹkẹ aro leyin nibẹyẹn. Bi a ba pe nọmba rẹ, iwọ ọmọkunrin, ti—ti o ko ba si lee…o dara, ṣaa na ọwọ rẹ soke, a o ri i wipe o de ihinyi. Ṣe o ye yin?

107 Ẹni melo ni o wà nibi ti ko ni kaadi adura, bẹẹni ara rẹ kò dá? Ẹ jẹ ki a ri ọwọ yin nibikibi. Nibi yii, o dara, ẹ na ọwọ yin soke. Ṣe ẹ gbagbọ? Bi wọn ṣe n to wọn lẹsẹẹsẹ, ṣe ẹ gba Eyi gbọ, wipe ọkannaa ni Oun lana, ati titi lae? Ẹni melo? Ẹ wo awọn oniwaasu wọnyi; njẹ Iwe Mimọ ko ha sọ loni, ẹyin ara, wipe Oun ni Olori Alufaa ti ko ṣaimọ ailera wa? Ṣe bẹẹ ni? Ẹni melo ni o gba iyẹn gbọ, ẹ na ọwọ yin soke? Oun ni Olori Alufaa ti o mọ ailera wa.

108 Njẹ ti Bibeli ba wipe, “Ọkannaa ni Oun lana, loni, ati titi lae,” ẹni melo ni o gba iyẹn gbọ? Njẹ bawo ni Oun yoo ti ṣe loni? O nilati

ṣe gẹgẹbi O ti ṣe lana. Ṣe bẹẹ ni? Nibo ni Ó wà ni aṣalẹ yii? O joko lọwọ ọtun Ọlanla, iyẹn ara Rẹ; Ẹmi Mimọ wà nibi ninu ile yii, lati sọ Oun di mimọ.

109 Ẹ kiyesi i, ki ẹ si wo ibi. Ki lo ṣẹlẹ, nigbati ẹnikan fi ọwọ kan aṣọ Rẹ nigba yẹn, ani obinrin kan lọjọ kan? Ko ni kaadi adura, ki a kuku sọ bẹẹ, ṣugbọn o fi ọwọ kan aṣọ Rẹ. Nigbati o si fi ọwọ kan aṣọ Rẹ, Jesu yiju pada, O wipe, “Tani o fi ọwọ kan Mi?”

110 Peteru ba A wi, o ni, “Eeṣe, Oluwa, iyẹn ko mu ọgbọn dani. Kini, gbogbo eniyan ni o n gbiyanju lati fi ọwọ kan Ọ. Eeṣe ti O fi wipe, ‘Tani o fi ọwọ kan Mi?’”

111 O ni, “Ṣugbọn mo ṣe akiyesi wipe aarẹ mu Mi.” Ẹni melo ni o mọ iyẹn? *Àṣẹ*, eyiti o tumọ si “okun,” jade lati ara Rẹ. “O rẹ Mi, ẹnikan fi ọwọ kan Mi pẹlu ifọwọkan ti o yatọ.” O yiju pada, O si wo ijọ eniyan titi ti O fi ri ibiti igbagbọ naa ti wa.

112 Gbogbo eniyan ni o n fi ọwọ kan-an lara wipe, “Ah, Rabbi, a gba Ọ gbọ,” ati gbogbo nkan wọnyi.

113 Ṣugbọn ẹnikan wà ti o gba A gbọ gidigidi. O fi ọwọ kan aṣọ Rẹ, o si gbagbọ wipe a ti mu oun lara da, nitoriti o sọ ninu ọkan rẹ wipe bi oun ba lee ṣe bẹẹ, ohun ti yoo ṣẹlẹ niyẹn.

114 O yiju pada, O si wo ijọ eniyan titi ti O fi ri i, O si wipe…O sọ fun-un wipe isun ẹjẹ rẹ ti dawọ duro, ati wipe a ti wo o san. Ṣe bẹẹ ni? Ni bayi, bi O ti ṣe niyẹn, laarin ijọ eniyan.

115 Ni bayi, emi n sọ wipe Oun kò kú, O wà laaye loni gẹgẹbi O ti wa laaye lati ẹyin wá. Bibeli sọ, Jesu sọ funra Rẹ wipe, “Gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Sodomu, bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de.”

116 Ẹ wo o, ko si iru ẹbun ti Ọlọrun lee ni loke nibi, ẹbun kan nilati wà nisalẹ nibẹyẹn pẹlu, lati dahun si i. O lọ si aarin ilu kan, Bibeli si wipe, “Ọpọlọpọ awọn nkan ni Oun ko lee ṣe nitori aigbagbọ wọn.” Ṣe bẹẹ ni? Bakannaa ni loni. Iwọ nilati gba A gbọ. Iwọ ṣaa nilati gba A gbọ. Ọna kanṣoṣo ti o lee gba ṣe e niyẹn.

117 Ṣe ila adura ti ṣetan? Ki gbogbo eniyan wà ni tọwọtọwọ fun iṣẹju bii mẹwa. N ko mọ boya mo lee de ọdọ gbogbo wọn, eniyan bii mẹẹdọgbọn tabi ọgbọn ni o naro si ibẹyẹn. Ṣugbọn lori ìlà adura, olukuluku ẹyin ti ẹ wà lori ila adura, ti ẹ si mọ wipe mo jẹ alejo si yin, wipe n ko mọ ohunkohun nipa yin, ẹ na ọwọ yin soke. Olukuluku ẹniti o wà lori ila adura.

118 Laarin ijọ eniyan, ẹyin ti ẹ mọ wipe n ko mọ ohunkohun nipa yin, ẹ na ọwọ yin soke. Njẹ nisisiyi, ohun ti mo n gbiyanju lati sọ niyi, ẹyin ọrẹ. Oun niyi bayi. Gbogbo awọn oniwaasu wọnyi wa lori pẹpẹ. Kristi ni o ṣe ileri yii. A si ti kọ ọ. Nigbawo ni yoo wa si imuṣẹ?

Ni ikẹyin ọjọ, ṣaaju ki Oluwa to de. Ṣe bẹẹ ni? O nilati wa si imuṣẹ ni igba naa.

119 Ọrọ ti a sọtẹlẹ fun ọjọ oni niyẹn. Ki i ṣe imọlẹ Luther; ki i ṣe imọlẹ Wesley; bẹẹni ki i ṣe imọlẹ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. O ti sun siwaju si i bayi. Imọlẹ Luther dara; imọlẹ Ijọ Eleto dara; imọlẹ Ijọ Onitẹbọmi dara, ani gbogbo wọn, ti Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ naa dara. Oniruuru eniyan ni o joko sibi yii ni aṣalẹ yii. Ki i ṣe—ki i ṣe—ki i ṣe eniyan kọọkan. Njẹ ti…

120 O ko lee sọ ohunkohun fun ijọ Eleto nipa Luther, nitoripe oun gbagbọ ninu isọdimimọ, Luther ko si gbagbọ bẹẹ. Ṣe o ye yin?

121 O ko lee sọ fun ọmọ Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ wipe "isọdimimọ nikan ni gbogbo rẹ," oun ti ri imubọsipo awọn ẹbun. Oun ki yoo gba iyẹn gbọ. Rara, oun ti ni ohun ti o pọ ju iyẹn lọ. Ṣe o ye yin? Igba ijọ ti o gbẹyin ti a ni niyẹn, Bibeli si wipe ki yoo si igba ijọ kankan mọ.

122 Ṣugbọn ipejọpọ awọn eniyan kan yoo wa, ibẹ si ni a wà yii. Ni bayi, ẹ ranti àmì ti o kẹyin. Ṣe awa n foju soṇa fun Ọmọ ileri naa? Ẹ na ọwọ yin Ṣe ẹ gbagbọ wipe ẹyin ni Iru-ọmọ Abrahamu nipa wíwà ninu Kristi? Ẹ na ọwọ yin soke. Njẹ nigbanaa, ẹyin Iru-ọmọ Abrahamu, ẹ gba àmì yin! Ko si ni Babiloni, ko si ninu ijọ ẹlẹkọ-adamọ. Aarin yin nibi ni o wà, awọn ti ko si ninu ibajẹ ti o wa ni ibẹyẹn. Ẹ gba a gbọ!

123 Obinrin kan niyi, alejo patapata ni o jẹ si mi, bii ọjọ ori kannaa ni a jọ jẹ. Emi ko ri obinrin naa ri ni gbogbo ọjọ aye mi. Iba ṣe wipe mo lee mu obinrin naa lara da ni, emi iba ṣe bẹẹ, iyẹn ti o ba n ṣe aisan. Emi ko mọ ohunkohun nipa rẹ. Njẹ ẹ ri i ti o na ọwọ rẹ soke ni iṣẹju melo kan sẹyin? Emi—emi ko ri i ri. O kan ṣaa jẹ obinrin kan ti o duro sibẹyẹn.

124 Loni, wọn sọkalẹ wa sibi yii, wọn si ko ọpọlọpọ awọn kaadi adura wá, wọn da gbogbo rẹ ru papọ, wọn si n fun awọn eniyan. Ẹnikan yoo gba nọmba kinni nibi, nọmba kẹwa nibẹyẹn, nọmba kẹẹdogun, nọmba keje, nọmba…bẹyẹn ṣaa. Gbogbo rẹ ni wọn n daru papọ, niwaju yin, lojoojumọ. Nigbati a ba si n pe wọn, a n pe wọn lati ibi gbogbo. Ṣe o ye yin? Ni bayi, o ko nilo lati ni kaadi adura, iwọ ṣaa joko sibẹyẹn, ki o si gbagbọ. Kini ṣe ti…

125 Ja ara rẹ ni eekanna ni aṣalẹ yii, ẹ jẹ ki a ṣe iwadi wakati ti a n gbe inu rẹ. Ṣe o ye yin? O ti fẹrẹ pari bayi, ẹyin ọrẹ. O ti fẹrẹ pari!

126 Njẹ ti Ọlọrun Abrahamu ba ji Jesu Kristi dide kuro ninu oku, ti Jesu yẹn si ṣe ileri wipe ni ikẹyin ọjọ, awọn àmì kannaa ti Abrahamu…ti Angẹli (eyiti i ṣe Ọlọrun ninu ẹran-ara eniyan) ṣe niwaju Abrahamu, ni kete ki ọmọ ileri naa to de, Jesu sọ pe nkan kannaa yoo ṣẹlẹ loni.

127 Ni bayi, a ri àdó olóró ati awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ, ati gbogbo awọn wọnni, ati inu ibajẹ ti wọn wa. A ri Billy Graham nibẹyẹn, pẹlu Oral Roberts, ati gbogbo awọn eniyan wọnyẹn nibẹyẹn; ojisẹ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ati ojisẹ awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ nibẹ, a ri gbogbo ohun ti o n ṣẹlẹ, wọn n fi àmì han. Billy Graham, ẹlẹkọ ẹsin pọ́nbélé ni, ohun ti awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ gbagbọ niyẹn. Oral Roberts, oluwosan pọ́nbélé ni, ohun ti awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ…

128 Ṣugbọn ẹ wo o, nkan miran wa ti a ṣe ileri rẹ fun Iru-ọmọ Abrahamu. Awọn yẹn wa laarin awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ; nkankan wà ti o yẹ ki o ṣẹlẹ *lẹyin ode* awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ, oun ni kiko awọn eniyan jọ. A o fi iyẹn silẹ di aṣalẹ ọla.

129 Ẹ kiyesi i, emi ko mọ obinrin yẹn. Emi yoo kọ ẹyin mi si i. Bi Oluwa Ọlọrun yoo ba sọ nkankan fun obinrin yẹn, boya o jẹ—boya ọrọ idile rẹ̀ ni, boya ọrọ owo ni, boya aisan ni; emi ko mọ. Oun yoo mọ boya otitọ ni tabi bẹẹkọ.

130 Ti Oun yoo ba ṣe nkan kannaa ni aṣalẹ yii, eyiti O ṣe nigbayẹn, ṣe ẹyin yoo gbagbọ ninu Ọlọrun ti…ti Jesu Kristi ṣe ileri wipe yoo wà nibi ni ikẹyin ọjọ? Ẹni melo ni o gbagbọ wipe o dabi ẹni pe inu Sodomu ni a n gbe, nigbati gbogbo aye ti wà ni ipo Sodomu? Ẹni melo ninu yin ni o gbagbọ wipe Otitọ ni ohun ti mo sọ fun yin ni aṣalẹ yii jẹ? Njẹ, ẹyin Iru-ọmọ Abrahamu, ẹ gba Ọlọrun gbọ!

131 Njẹ ki a lee mu u kuro ninu ọkan yin wipe mo n gbiyanju lati sọ nkankan fun obinrin naa, nipa wiwo oju rẹ̀, tabi lati mu ohunkohun nipa àfọṣẹ kuro, tabi ohunkohun ti ẹ fẹ mọ. Ẹnikẹni ti o ba mọ nipa afọṣẹ yẹ ki o gbọn ju bẹyẹn lọ. Ṣe o ye yin? Ṣe o ye yin? Njẹ ẹyin ri alafọṣẹ ki o maa waasu Ihinrere ri? Ṣe ẹ ri abokusọrọ ki o maa waasu Ihinrere ri, ki o maa ṣe iṣẹ-àmì ati iṣẹ-iyanu, ki o maa kede wipe ọkannaa ni Jesu Kristi? Rara.

132 Ẹ ri i, o kan jẹ…awọn eniyan ni o n ro bẹẹ. Ẹ ri i, wọn fọju ni. Ṣe ẹ gbagbọ wipe wọn lee fọju? Bibeli sọ wipe wọn yoo fọju. Ṣe bẹẹ ni? “Olorikunkun, ọlọkan giga, olufẹ faaji ju olufẹ Ọlọrun lọ, ọdalẹ, olufisun eke, alainitẹlọrun, olukẹgan awọn ẹni rere, wọn ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun, ṣugbọn wọn n ṣẹ́ Agbara rẹ.”

133 Jesu ko ha sọ, ni Matthew 24:24, wipe awọn ẹmi mejeeji ni ikẹyin ọjọ yoo fẹrẹ tan awọn Ayanfẹ jẹ, ti o ba ṣee ṣe? Ṣugbọn ko ṣee ṣe. Wọn ti wà ninu èrò Ọlọrun lati atetekọṣe, wọn si jẹ ara Ọlọrun.

134 Ni bayi, Ọlọrun Abrahamu, Isaaki, ati Jakọbu, jẹ ki o di mimọ ni aṣalẹ yii wipe mo n sọ Otitọ nipa Rẹ. Iwọ ni, Oluwa. Pẹlu ireleẹ, jẹ ki awọn iranṣẹ Rẹ lee mu èrò tiwọn kuro loju ọna, ki Iwọ lee lo ara wa fun Ogo Rẹ. Ni Orukọ Jesu, Ọmọ Ọlọrun. Amin.

135 Kini ẹbun? Ki i ṣe nkankan ti o lee mu, ki o si loo bi o ṣe fẹ. Rara, rara. Mímọ bi o ṣe lee kuro loju ọna ni, ki Ọlọrun lee lo ọ. Ẹbun ni ki o mu ara rẹ kuro, nigbanaa, Ọlọrun lee lo ọ.

136 Obinrin ti o wa lẹyin mi yoo ku lẹṣẹkẹṣẹ ti a ko ba wo o san. Ọkunrin miran ti gbadura fun obinrin ti o wa lẹyin mi, laipẹ yii. O ni arun jẹjẹrẹ. Ori ọyan rẹ ni arun jẹjẹrẹ naa wa, ati ninu èdò-fóró rẹ. A ṣẹṣẹ gbadura fun-un laipẹ yii ni, o si n gbiyanju lati fi igbagbọ gba a wipe a ti mu oun lara da. BAYI NI OLUWA WI niyẹn! Ṣe otitọ niyẹn, arabinrin? [Arabinrin naa sọ pe, "Bẹẹni, otitọ ni dajudaju."—Onkọwe.] Ti o ba ri bẹẹ, ju—ju ọwọ rẹ si ijọ. Ọlọrun Abrahamu wà laaye sibẹ! O dara, lọ gbagbọ ninu ohun ti o gbagbọ, ara rẹ yoo si dá. Amin.

Ṣe ẹ gbagbọ? Ẹ lee sọ pe, "Awọn ijọ nkọ?"

137 Obinrin ti o joko sibi yii pẹlu…ni opin ila yẹn, obinrin keji ti o wa nibẹyẹn. Nigbati mo yiju pada si ibẹyẹn, mo ri nkankan, nkankan ní apá rẹ̀, èrọ ti a fi n yẹ ìfuńpá wo ni. O ni ifunpa gíga. Ṣe bẹẹ ni, arabinrin? Na ọwọ rẹ soke. Ti o ba gbagbọ, ifunpa giga rẹ yoo lọ silẹ. Ọlọrun Abrahamu n bẹ loju agbo sibẹ. Ohun ti O jẹ tẹlẹ naa ni, Ọrọ Ọlọrun fun ọjọ oni!

138 Bawo ni? Ṣe o gbagbọ bayi? Ni igbagbọ ninu Ọlọrun! O dabi ẹni pe ọmọde ni. Ọlọrun mọ ọkan rẹ, ọdọmọbinrin, emi ko mọ ọ. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee fi ohun ti o n ṣe ọ han mi? Ṣe iwọ yoo gba Oun gbọ ti mo ba ṣe bẹẹ? Ki i ṣe fun ara rẹ, fun ẹlomiran ni, iyẹn ni arakunrin rẹ. Ọrọ rẹ̀ lagbara, ó wà ni ilu kan ni iha ariwa, Tulare ni. Ó wà ni ile iwosan, o ni arun jẹjẹrẹ inu ẹjẹ, awọn dokita ti fi silẹ wipe ki o ku. Ko si ireti kankan rara. Bẹẹ ni. Ṣe o gbagbọ? [Arabinrin naa sọ pe, "Bẹẹni."—Onkọwe.] O dara. Kini o wa lọwọ rẹ? Mu nkan yẹn, ki o fi lee lara. Maṣe ṣiyemeji, gbagbọ. Amin.

139 Ṣe o gbagbọ? Emi ko ri obinrin naa ri ni gbogbo ọjọ aye mi. Ṣugbọn Ọlọrun jẹ Ọlọrun sibẹ! Ẹ sọ fun mi, eniyan wo ni o lee ṣe nkan yẹn. Ko si ninu àbùdá eniyan lati ṣe bẹẹ. Ọlọrun ni, ẹniti Jesu Kristi ṣe ileri wipe yoo wà nihin ni ikẹyin ọjọ, ti yoo si fi ara Rẹ han (ki Iru-ọmọ Abrahamu to de) gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Sodomu.

140 Emi ko mọ obinrin yii, alejo ni a jọ jẹ si ara wa, mo ro wipe igba àkókó ti a o jọ pade niyi. Ṣe o gbagbọ wipe iranṣẹ Rẹ̀ ni mo jẹ? [Arabinrin naa sọ pe, "Bẹẹni."—Onkọwe.] Ṣe o gba *eyi* gbọ wipe Ọrọ naa ni? ["Bẹẹni"] O si mọ bẹẹ, boya Ọrọ yii ṣì jẹ́ olumọ èrò inu ati ète ọkan, ṣe bẹẹ ni? Ọrọ naa ni Oluwosan pẹlu, ti o ba lee gba A gbọ. O gba A gbọ. Ojiji dudu kan bo iwọ naa mọlẹ pẹlu. Arun jẹjẹrẹ ni. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee sọ ibiti arun jẹjẹrẹ naa wa fun mi? Inu ifun isalẹ ni ó wà, ohun ti dokita ti sọ niyẹn. Ṣe o gbagbọ bayi wipe a

o mu ọ lara da? Maa lọ, maṣe ṣiyemeji rara, Ọlọrun yoo si mu ọ lara da. Amin.

141 Ṣe gbogbo yin gbagbọ? Ohun ti O ṣe ileri lati ṣe gan-an niyẹn! Ẹ ni igbagbọ ninu Ọlọrun, ẹ maṣe ṣiyemeji.

142 Alejo ni a jọ jẹ si ara wa. Emi ko mọ ọ. Ti a ba jọ jẹ alejo si ara wa, jẹ ki ijọ mọ bẹẹ, a o di ọwọ ara wa mu. Emi ko ri obinrin naa ri ni gbogbo ọjọ aye mi.

143 Ṣe ẹ gbagbọ nibẹyẹn? Ṣe ẹ gbagbọ wipe Jesu Kristi ni? Kini? Ọrọ Rẹ̀ ni. Nigbati awọn eniyan wọnyi ba kọ Ọ, ki i ṣe eniyan ni wọn n kọ, Ọrọ yẹn ni wọn n kọ. Ọrọ ti o wa ni ita ni, ti ko lee pada wọle.

144 Alejo ni obinrin naa jẹ si mi. Emi ko ri i ri ni gbogbo ọjọ aye mi. Oluwosan ni Ọlọrun. O lee ma jẹ nitori iwosan, o lee jẹ nitori nkan miran, ṣugbọn ti Ọlọrun yoo ba ṣalaye ohun ti o n ṣe ọ fun mi, ṣe iwọ yoo gba mi gbọ? Ohun àkókó ti o n fẹ ki a gbadura fun ni wipe, eti kan n dun ọ. Ọkan ninu awọn eti rẹ, o ko lee fi gbọran. Bẹẹ ni. Otitọ niyẹn. Ẹwẹ, o tun ni iwa kan, o si fẹ fi opin si iwa yẹn, iyẹn ni sìgá mimu. Fi ọmọ-ika rẹ sinu eti rẹ ti o dara, o dara bẹẹ, eti rẹ ti o dara ni o. O dara. Ni bayi, gba Ọlọrun gbọ ki o si maa ba ọna rẹ lọ, maṣe…bẹẹni iwọ ki yoo mu siga kankan mọ, ti o ba gbagbọ. Maa lọ, ki Oluwa bukun fun ọ.

Ṣe ẹ ri ohun ti o ṣẹlẹ. Oun ko ha wà lotitọ bi?

145 Emi ko mọ ọ, alejo ni a jọ jẹ si ara wa. Emi ko ri ọ ri ni gbogbo ọjọ aye mi, ṣugbọn Ọlọrun mọ ọ. Ti Ọlọrun ba lee sọ nkankan fun mi nipa rẹ, ṣe iwọ yoo gbagbọ?

146 Ṣe gbogbo ijọ yoo gbagbọ? Njẹ ẹnikẹni wa nibẹyẹn ti o mọ obinrin naa? Ẹnikẹni ha wa ninu ijọ ti o mọ obinrin naa bi? O dara, ẹ o mọ boya otitọ ni eleyi tabi bẹẹkọ. O yẹ ki iyẹn yanju ọrọ. O yẹ ki eleyi sọ otitọ.

147 Ẹ ti ri ohun ti o ṣẹlẹ ni iṣẹju melo kan seyin. Ṣe ẹ ri i? Ó kan jẹ… Mo n fi. Ṣe ẹ ri i? O kan jẹ, ohun gbogbo ti n dabi ifoju si mi. Imọ-ẹmi-yatọ ni. Ẹmi Mimọ ni. Ki i ṣe emi. Ọrọ ti a ṣe ileri Rẹ fun ọjọ oni ni. Ko ti i ṣẹlẹ lati igba awọn aposteli, ko ṣẹlẹ ri. Ṣugbọn a sọ nibikan pe, “Ni kete ki Ọmọ eniyan to de. Gẹgẹbi o ti ri ni ọjọ Lọọti, bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de.” Awọn alaigbagbọ ko gba A gbọ. A ko reti wipe ki wọn gba A gbọ. Ṣugbọn awọn onigbagbọ gba A gbọ!

148 Ti Ẹmi Mimọ yoo ba fi eleyi han, ẹni melo ni yoo gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin, ẹ na ọwọ yin soke?

149 O ni ipalara kan. O ti ni ijamba ọkọ, ó ti jẹ ki awọn egungun ẹyin ọrùn rẹ kan yẹ. Ọkan ninu awọn kińdiǹriń rẹ ti yẹ pẹlu. Bẹẹni, tabi

bẹ̀ẹ̀kọ? [Arabinrin naa sọ pe, “Bẹ̀ẹ̀ni, sà.”—Onkọwe.] Ṣe o gbagbọ? [“Bẹ̀ẹ̀ni, sà.”] Ara rẹ yoo dá. Ẹ yin Oluwa.

150 Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun n wo kíńdiǹriń sàn? Maa lọ nigbanaa, ki o si gba iwosan rẹ.

151 Wa, arabinrin. Wo ibi yii. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun n wo aisan ọkan sàn? O dara, ma ba ọna rẹ lọ, ki o si gbagbọ, ọkan rẹ yoo gba iwosan.

152 Wá nibi. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee wo ẹyin rẹ sàn, ki Ó sì mú ọ lara da? Maa lọ, ki o si gba a gbọ.

Ẹ ṣaa gba Ọlọrun gbọ, gbogbo ohun ti ẹ nilati ṣe niyẹn!

153 Wa, arabinrin. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun n wo inu rirun sàn? Maa lọ, lọ jẹ ounjẹ alẹ rẹ, gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ.

154 Wá. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee wo aromọleegun sàn? Maa lọ nigbanaa, gbagbọ, ki o si ṣe…Ọlọrun yoo si mu ọ lara dá.

155 O dara, wá. Ṣe o gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ? O gbagbọ? Aromọleegun tun ni. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee mu ọ lara da? Maa lọ, gba a gbọ, sọ pe, “Ẹ ṣeun, Oluwa.”

Ẹni melo ni o gbagbọ nibẹyẹn? Ṣe ẹ gbagbọ?

156 Obinrin ti o joko sibi yii, ti o wọ aṣọ pupa, ti o na ọwọ rẹ soke nibi yii, ifunpa giga ni o n pọn ọ loju. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee mu ọ lara da? O gbagbọ? O dara. Gbe ọwọ re le obinrin ti o wa ni ẹgbẹ rẹ nibẹyẹn, ki o si sọ fun-un wipe ohùn rẹ yoo pada dara. Amin.

Bi o ṣe ri niyẹn. Amin. Ṣe ẹ gbagbọ? Ẹ ni igbagbọ!

157 Ọkunrin kan ni o joko sibi yii, o ni ìsun ẹjẹ. Ṣe o gbagbọ, iwọ alagba ti o joko sibi yii? Bẹẹ ni, o ni isun ẹjẹ. Ṣe o gbagbọ wipe yoo sàn?

158 Obinrin ti o joko si ẹgbẹ rẹ naa ni isun ẹjẹ pẹlu, o si ni ẹyin didun. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo mu ọ lara da? O gbagbọ? Na ọwọ rẹ soke, ki o si gba a. Gbagbọ.

159 Obinrin ti o wa lẹgbẹ rẹ yii ni iṣoro pẹlu ẹṣẹ ati itan rẹ. Ṣe o gbagbọ wipe otitọ niyẹn, arabinrin? O gbagbọ wipe a o mu ọ lara da? Na ọwọ rẹ soke, ki o wipe, “Mo gba a.”

160 O dara, obinrin ti o wa lẹgbẹ rẹ ni kokoro inu ẹjẹ. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo kokoro inu ẹjẹ yẹn san, iwọ ọdọmọbinrin ti o lo awò-ojú? Na ọwọ rẹ soke, ki o wipe, “Mo gba a.” O dara, gba a gbọ.

161 Obinrin ti o wa lẹgbẹ rẹ ní àrùn inu kíńdiǹriń. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo kindinrin yẹn san, arabinrin? O dara, na ọwọ rẹ soke, ki o si gba a.

162 Ọmọbinrin kekere ti o wa lẹgbẹ rẹ ni gbẹ̀gbẹ̀ ọrùn. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo gbẹgbẹ ọrun yẹn sàn nibẹyẹn? Na ọwọ rẹ soke, ki o gba a.

163 Ẹni melo ni o gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin? Ẹ dide duro lori ẹsẹ yin, ki ẹ gba a. Ẹ dide duro Niwaju Ọlọrun Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu.

164 Ni Orukọ Jesu Kristi Oluwa, jẹ ki Ẹmi Mimọ sọkalẹ sinu ile yii nisisiyi, ki o si mu gbogbo awọn ti o wa Niwaju Oluwa lara da!

64-0205 Ọlọ́run Ni Olùtúmọ̀ Ara Rè
Kern County Fairgrounds
Bakersfield, California Orilẹ-Ede Amẹrika

YORUBA

©2026 VGR, ALL RIGHTS RESERVED

Voice Of God Recordings
P.O. Box 950, Jeffersonville, Indiana 47131 U.S.A.
www.branham.org

Aṣẹ Onkọwe

Gbogbo ẹtọ́ si iwe yii jẹ ti òntẹ̀wé. A lee tẹ iwe yii lori ẹrọ-ìtẹwé abẹ́-ilé fun ìlò ara ẹni, tabi lati fi funni, lọfẹ, gẹgẹbi ohun-èlò lati tan Ihinrere Jesu Kristi kalẹ. A ko lee ta iwe yii, tabi ki a ṣe èdà rẹ ni òpòlọpọ̀, tabi ki a gbe e sori ẹrọ ayélujára, tabi ki a fi pamọ́ si ibiti a tun ti lee faa jade pada, tabi ki a tumọ rẹ si awon èdè miran, tabi ki a lo o lati fi beere fun owó, lai si ìfààyègbà ti a kọ sinu iwe lati ileiṣẹ Ohùn Ọlọrun Tí A Ká Silẹ.

Fun awọn alaye si tabi awọn ohun èlò miran, ẹ kọwe si:

VOICE OF GOD RECORDINGS
P.O. BOX 950, JEFFERSONVILLE, INDIANA 47131 U.S.A.
www.branham.org